# Bibeli fun awon omode

## Ogoji Odun



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest
Alastair Paterson

Olu'lo: Lyn Doerksen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.



Nigba ti Olorun ti gba awon omo Israeli la kuro ni Ijibiti Mose siwaju awon eniyan naa lati sin Olorun O se akojopo orin iyin "Emi o korin si Oluwa nitori ti o mu ni bori togo togo" Mose korin fun gbogbo ohun nla ti olorun ti se fun awon omo israeli.

OGO FUN
OLORUN ALLELYA!



Lehin ojo meta ni asale awon eniyan ti ohungbe n gbe ri adagun. Sugbon won ko le mu omi kikoro naa. Kaka ki won gbadura awon eniyan naa bere si se awawi. Olorun je alaaanu O je ki omi naa dara fun mimu.





Awon eniyan naa si bere si sawawi ninu ohun gbogbo. "Awa ni ounje ni Ijibiti, ni Aginju ebi ni yoo pa wa ku." Won kigbe. Ni irole ojo naa Olorun da eye aparo sile, Awon eniyan naa si bere si ko won.



Ni owuro ojo keji Olorun ro ojo mana sile. O dabi akara ti o dun bi oyin. Ni ojoojumo ni mana n ro sile lati ko ni ona

bayii Olorun bo awon eniyan re ni ajinju.

Won gbodo gba Olorun gbo fun ipese ounje ni ojoojumo.  Awon eniyan miran ko akokun mana, Bi o tile je pe Olorun so pe akokun naa yoo baje loru.



Dajudaju mana ti ana ti kun fun idin, ayafi ojo Sabati nikan. Ni ojo keje awon eniyan naa sinmi won si je mana ti ana.



Olorun bojuto awon omo Israeli ni asale O fun won ni ounje ati omi, O si daabobo won lowo awon ota won.  Nigba ti won doju ija ko awon ara Amaleeki,

awon Israeli si bori ogun Nigbogbo igba ti Mose ba gbe Opa Olorun soke.





Olorun so fun awon Omo Israeli "Ti eyin ba gba ohun mi gbo eyin yoo je eniyan oto fun mi," Gbogbo ohun ti Olorun so ni a o se, awon eniyan naa so fun Mose. Won si de si isale oke Sinai won duro Nigba ti Mose lo pade Olorun.



Mose si wa pelu Olorun fun Ogoji ojo Olorun si ko ofin mewaa sara walaa okuta O so fun Mose bi O se fe ki awon eniyan naa ma gbe.

1. “Iwo ko gbodo ni Olorun miran pelu mi.”

2. “Iwo ko gbodo ya erekere tabi fi Oribale fun erekere.”

3. “Iwo ko gbodo pe Oruko Olorun lasan.”

4. “Ranti Ojo Isinmi lati ya a si mimo.”

5. “Bowo fun Baba ati Iya re.”

6. “Iwo ko gbodo paniyan.”

7. “Iwo ko gbodo se Pansaga.”

8. “Iwo ko gbodo jale.”

9. “Iwo ko gbodo paro.”

10. “Iwo ko gbodo seke.”



Nigba ti Mose wa pelu Olorun lori oke Sinai Awon omo Israeli se eyi ti o buru gidigidi, won pase fun Aaroni ki o se ere, egboro maalu... won si n sin ere naa dipo Olorun, Olorun si binu si won, beeni Mose naa pelu.



Nigba ti Mose ri ere egboro maalu naa ti awon eniyan si n jo, O le waala okuta ti o wa ni owo re mole. Ninu ba bi Mose fo ere naa mole, Awon Okunrin buruku naa ti won sin orisa naa di pipa.

Olorun paaro waala Okuta mejeeji, O so fun Mose pe ki o ko ago, ago ti o tobi pelu ogba yika Nibi ti Olorun yoo maa gbe pelu awon eniyan re Won yoo si maa sin Olorun nibe Owon kurukuru ati ina fi han pe Olorun wa pelu won nibe.



Bi won se n sunmo ile Kenaani Mose ran awon ami mejila lati wo ile ti Olorun se ileri fun awon eniyan re. Gbogbo awon ami gba pe ile naa dara, sugbon awon meji pere Josua ati Kalebu gba pe awon yoo gba ile naa pelu iranlowo Olorun.



Awon ami mewaa yooku beru awon ilu Olodi ati awon omiran ile naa "A le gba ile naa" won kun. Won ti gbagbe awon nnkan nla ti Olorun se lati mu won jade lati ile Ijibiti.



Opo Awon eniyan tele awon ami mewaa ti ko ni igbagbo.  Won kigbe won si tun fe pada lo si Ijibiti, won tile gbiyanju won fe pa Mose.



Olorun daabobo Mose ko je ki won ri pa, Nigba naa Olorun so fun awon eniyan naa pe fun Ogoji odun e o maa je alarinkirin ni aginju Kalebu ati Josua Nikan ati awon omo weere yin Nikan ni yoo wa laye lati wo ile ti eyin san.



Ogoji Odun

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Ekisodu ori keedogun,
Numeri ori kerinla

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.